# MAJẸMU TITUN

Heberu 9:6-28

## ẸKỌ 440 -- FUN AGBA

AKỌSORI: "Nitori Kristi kò wọ̀ ibi mimọ́ ti a fi ọwọ́ ṣe lọ ti iṣe apẹrẹ ti otitọ; ṣugbọn o lọ si ọ̀run pãpã, nisisiyi lati farahan ni iwaju Ọlọrun fun wa" (Heberu 9:24).

### Ibi Mimọ́

**"Njẹ nigbati a ti ṣe ètò nkan wọnyi bayi, awọn alufa a mã lọ nigbakugba sinu agọ́ ekini, nwọn a mã ṣe iṣẹ isin" (Heberu 9:6).**

Eyi ti a pè ni "agọ́ ekini" ni Ibi Mimọ́. Ninu yara yii ni a fi ọpa fitila wura si ni ọwọ́ osi bi a ba ti wọle, ati tabili akara ifihàn ni ọwọ ọtun. Ni iwaju aṣọ ikele ni pẹpẹ turari wà.

### Akara Ifihàn

Ni ọjọọjọ Isinmi ni a n paarọ akara ifihàn. Akara mejila ni o wà nibẹ, ti o wà ni ila meji ni mẹfa-mẹfa, eyi ti o duro fun awọn ẹya Israẹli mejila. Bi a ti n parọ wọn bẹẹ ni a n kó awọn ti o wà nibẹ tẹlẹ kuro ti a si n kó wọn fun awọn alufaa. O tọna fun wọn lati jẹ akara ifihan.

A sọ itumọ eyi fun wa nigba ti Jesu wi pe:

**"Emi ni onjẹ iye ni ti o ti ọrun sọkalẹ wá: bi ẹnikẹni ba jẹ ninu onjẹ yi, yio yè titi lailai: onjẹ na ti emi o si fifunni li ara mi, fun ìye araiye." (Johannu 6:51).**

Ni iwọn igba ti o jẹ pe Jesu ni Ọrọ naa ti o wá ninu ara, a ri itumọ ti o ṣe deedee fun akara naa: Ọrọ Ọlọrun ni. Jobu ni Ọrọ naa jẹ́ ohun pataki fun oun ju ounjẹ oun lọ. Jakejado gbogbo iṣẹ-isin ninu Agọ ni a ri i pe ohun ti o ṣe pataki fun gbigbe ara ró jẹ apẹẹrẹ ohun ti o ṣe pataki lati gbé ẹmi ró.

### Pẹpẹ Wuwa

Pẹpẹ wura jẹ́ pẹpẹ turari. Ninu iṣẹ-isin wọn ojoojumọ ni oroowurọ ati alaalẹ ni awọn alufaa ni lati maa fi turari jona lori pẹpẹ yii. Alufaa ti o n ṣe iṣẹ-isin (awọn alufaa a maa ṣe iṣẹ-isin gẹgẹ bi ipa ti wọn, olukuluku a maa ṣe ti rẹ̀ nigba ti o ba kan an) yoo mú ẹ̀ṣẹ́ iná lati ori pẹpẹ idẹ wá ni ibi ti iná gbé n jó nigba gbogbo lai kú, yoo si fi i sinu awo turari rẹ̀. Awọn eniyan ro pe yoo fi awọn ẹ̀ṣẹ́ iná wọnyii si ori pẹpẹ wura lẹyin naa yoo si fi turari naa si ori rẹ̀.

A fi ohun ti pẹpẹ turari yii duro fun hàn ninu Ifihan ori 8 ni ibi ti angẹli kan duro ni iwaju pẹpẹ pẹlu awo turari wura ni ọwọ́ rẹ̀ ti o si fi turari naa kún adura awọn eniyan mimọ́; eefin turari naa pẹlu adura awọn eniyan mimọ́ si goke lọ si iwaju Ọlọrun. Turari jẹ́ apẹẹrẹ adura.

Eyi ni Onipsalmu n sọ nipa rẹ̀ nigba ti o wi pe:

**"Jẹ ki adura mi ki o wá si iwaju rẹ bi ẹbọ turari; ati igbé ọwọ mi soke bi ẹbọ aṣãlẹ" (Orin Dafidi 141:2).**

### Ibi Mimọ́ JUulọ ni Ọjọ Etutu

**"Ṣugbọn sinu ekeji ni olori alufa nikan imã lọ lẽkanṣoṣo li ọdún, ki iṣe li aisi ẹ̀jẹ, ti on fi rubọ fun ara rẹ̀ na, ati fun iṣina awọn enia" (Heberu 9:7).**

Ni iwaju Ibi Mimọ́ Julọ ni a so aṣọ ikele ni rọ̀ si, a ṣe e lọṣọ lọpọlọpọ, a fi awọn kerubu ṣe e lọṣọ. Olowo iyebiye ni ohun ti a fi ṣe lọpọlọpọ, a fi awọn kerubu ṣe e lọṣọ. Olowo iyebiye ni ohun ti a fi ṣe e . Ko swi ẹni ti o n lọ sibẹ afi olori alufaa nikan, lẹẹkan ni ọdun ni o si maa n lọ sibẹ ni Ọjọ Etutu. Awọn Ọmọ Israẹli a maa gbaawẹ ni ọjọ yii wọn a si maa pohunrere ẹkún ni iwaju Oluwa. O jẹ́ akoko ironupiwada fun orilẹ-ède wọn. Olori alufaa yoo lọ sinu Ibi Mimọ́ Julọ pẹlu ẹjẹ akọ maluu ti a pa lori pẹpẹ idẹ a si kọkọ ṣe etutu fun ẹ̀ṣẹ ti rẹ̀ lẹyin eyi fun ẹ̀ṣẹ awọn eniyan ati fun awọn alufaa. Yoo tun pada si ibi pẹpẹ idẹ ti o wà ninu agbala.

Ewure meji ni a o mú wá. Ọ̀kan ninu wọn ni a o pa; a si gbé ọwọ le ekeji a si jẹwọ ẹ̀ṣẹ awọn eniyan naa sori rẹ̀; lẹyin naa, a o lé ewurẹ yii lọ sinu aginju. Awọn ewurẹ mejeeji wọnyii jẹ́ apẹẹrẹ Jesu ẹni ti i ṣe ewurẹ idasilẹlọ wa ati irubọ fun wa.

**Apoti Majẹmu, Itẹ Aanu, ati Ṣẹkina**

Ibi Mimọ́ Julọ ni Apoti Majẹmu wà, ninu eyi ti awọn Walaa Okuta (ti a kọ Ofin si gbe wà). Lori ohun ti a fi bo Apoti Majẹmu naa ni awọn kerubu wà, awọn mejeeji dojukọ ara wọn, iyẹ wọn si n kan ara wọn. Wọn duro fun awọn angẹli. Nibẹ, wọn n bojuwo ilẹ wo Ofin ti o wà ninu Apoti naa. Idajọ Ọlọrun n beere pe ki eniyan dé odiwọn ti a fi lelẹ ninu Ofin, ṣugbọn ni aarin awọn Kerubu ni ati Ofin nì Itẹ Aanu wà. Wọn duro fun awọn awọn angẹli. Nibẹ, wọn n bojuwo itẹ wo Ofin ti o wà ninu Apoti naa Idajọ Ọlọrun n beere pe ki eniyan de odiwọn ti a fi lelẹ ninu Ofin. ṣugbọn ni aarin awọn Kerubu ni ati Ofin ni Itẹ Aanu wà. Eyi n ṣe apẹẹrẹ aanu Ọlọrun. Nigba ti awọn eniyan bá kuna lati rin deedee gẹgẹ bi ofin ati ilana Rẹ̀, afo aanu yoo ṣi silẹ fun wọn. Ninu Romu 3:25, ni ibi ti Paulu ti n sọrọ nipa Jesu, a ka a pe:

**"Ẹniti Ọlọrun ti gbe kalẹ lati jẹ ètutu nipa igbagbọ́ ninu ẹ̀jẹ rẹ̀,. . . . ."**

"Ètutu" jẹ́ orọ kan naa ti a lo fun Itẹ Aanu. Nipa bayii Jesu di Itẹ Aanu ki i ṣe fun awọn Ju nikan ṣugbọn fun gbogbo ayé. Ko si ohun kan ti o wà ninu gbogbo eto isin Agọ tabi awọn ohun elo inu rẹ̀ ti ko jẹ apẹẹrẹ fun ohun kan. Ko si ohun kan ti a kàn ṣe ni ainidi.

Loke Itẹ Aanu ni Ṣẹkina Oluwa ti n tàn, itaṣan iná ti o ga ju imọ ẹda lọ. Bi Israẹli ba ti pagọ, ọwọ̀n awọsanma ni ọ̀sán ati ọwọ̀n iná ni oru yoo duro ni oke Apoti Majẹmu. Eyi yii jẹ́ idaniloju pe Ọlọrun wà ni aarin wọn. Nitori naa Ibi Mimọ́ Julọ yii duro fun ibugbe Ọlọrun tikara Rẹ̀, kò si si ọ̀kan ninu awọn Ọmọ Israẹli ti o le sun mọ tosi rẹ̀, ki i tilẹ i ṣe awọn alufaa paapaa—ayafi olori alufaa nikan, oun paapaa lẹẹkan ni ọdun ni, ni Ọjọ Etutu.

Eyi rán wa leti ọrọ Paulu wọnni nigba ti o wi pe kò si ẹni kan ti o le sun mọ ogo Rẹ̀. [Wo 1 Timoteu 6:16].

**Akoko ti Ẹmi Mimọ́**

**"Ẹmi Mimọ́ ntọka eyi pé a kò ti iṣi ọ̀na ibi mimọ́ julọ silẹ niwọn igbati agọ́ ekini ba duro" (Heberu 9:8).**

Eyi n fi ye ni pe Agọ naa pẹlu gbogbo iṣẹ isin rẹ̀ jẹ ohun ti o wà fun igba diẹ. O tun n sọ fun ni nipa fifun ni ni Ẹmi Mimọ́, gẹgẹ bi a o ti ri i lai pẹ lati inu awọn ẹsẹ Ọrọ Ọlọrun miiran gbogbo. A kò fi ohun ti Ibi Mimọ́ Julọ yii duro fun hàn niwọn igba ti Agọ naa wà sibẹ, ṣugbọn eyi n fi hàn pe akoko kan n bọ̀ ti a o fi ohun ti o duro fun hàn gbangba. O tun fi hàn pe: igba ti akoko Ẹmi Mimọ́ bẹrẹ ni igba ti Jesu bẹrẹ Iṣẹ Alufaa Rẹ̀. Nitori idi eyi O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Ṣugbọn otitọ li emi nsọ fun nyin; Anfani ni yio jẹ fun nyin bi emi ba lọ: nitori bi emi kò ba lọ, Olutunu ki yio tọ̀ nyin wá: ṣugbọn bi mo ba lọ, emi o rán a si nyin" (Johannu 16:7). Nigba ti O goke lọ si Ọrun lati ori Oke Olifi, O wọ inu Agọ naa lati bẹrẹ iṣẹ Rẹ̀ keji, ti i ṣe Iṣẹ Alufaa. Ni akoko yii ni a rán Ẹmi Mimọ́ sọkalẹ.

**Apẹẹrẹ**

**"Eyiti iṣe apẹrẹ fun igba isisiyi gẹgẹ bi eyiti a nmu ẹ̀bun ati ẹbọ wá, ti kò le mu olusin di pipé, . . . ." (Heberu 9:9).**

Eyi mu ki a maa wadii pe: ki ni ire ti o wà ninu awọn ẹbọ wọnyii? Ki ni ṣe ti Ọlọrun ṣe ilana wọn bi a ko ba le ti ipasẹ wọn di pipé? O ni ohun ti o wà fun ni iwọn igba ti o n tọka si ohun ti ẹmi. Awọn irubọ ati ẹbọ wọnyii tikara wọn kò ni ire kan ninu; ọna ti awọn Ju si fi kuna ninu iṣẹ-isin ti Majẹmu Laelae yii ni pe wọn kuna lati ri Jesu Ẹni ti gbogbo irubọ wọnyii n tọka si. Ẹbọ ati irubọ wọn sọ apẹẹrẹ ti wọn duro fun nù kiki ẹbọ yii lasan ni wọn si n pọnle. Ojiji lasan ni ẹbọ yii jẹ́.

Jesu fi ilana Ounjẹ Alẹ Oluwa lelẹ. Eyi ni ọna kan fi ara jọ awọn ilana wọnyii ti o wà ni igba Majẹmu Laelae. Njẹ agbara kan ha wà ninu omi ọsàn ti a fún tabi akara ti a n lò ninu ilana yii? Rará! Awọn miiran wà ti wọn rò pe agbara wà ninu wọn. Ijọ Aguda ti dá ẹ̀kọ́ iyipada di-ohun miiran silẹ: eyi ni pe nipa iṣẹ iyanu kan, akara ati waini a maa yi pada di Ara ati Ẹjẹ Oluwa ti a ta silẹ. Awọn pẹlu ti ṣe ohun ti awọn Ju ṣe: wọn ti mu ohun ti Ọlọrun pinnu pe ki o jẹ́ apẹẹrẹ nipasẹ eyi ti a le ri aworan ohun airi kuro, wọn si ti sọ eyi ni di ohun sisin.

Ni akoko Eli, awọn Ọmọ Israẹli gbé Apoti Majẹmu lati inu Agọ, lodi si Ofin, wọn si gbé e wá si oju ogun. Ki ni ṣe? Nitori wọn rò pe Apoti Majẹmu nì ni agbára kan ati ipá kan ninu ti yoo fun wọn ni iṣẹgun lori awọn Filistini. Ọlọrun bá wọn wi nipa mimu ki wọn ṣubu pẹlu iparun nla. O si jẹ ki Apoti naa bọ́ si ọwọ awọn abọriṣa nitori wọn ti pa ohun ti o duro fun dà si ohun miiran, wọn si ti rò pe agbára wà ninu Apoti naa tikara rẹ̀.

Nigba ti awọn ẹlẹsin kan ba sọ ohun ti o wà fun apẹẹrẹ tabi àmi di ohun sisin irú ẹsin bẹẹ ti pada di ibọrișa - kò si orukọ miiran fun un. Apoti majẹmu ti di orișa fun awọn Ju ni akoko yii. Anfaani kan ṣoṣo ti o wà ninu awọn ilana, irubọ ati ẹbun wọnyii ni pe wọn jẹ́ itọka si ohun ti ẹmi.

Ọlọrun ti fi Agọ pẹlu gbogbo ilana isin ti o ṣe finnifinni bẹẹ lelẹ ni ọna ti o fi le ṣe eniyan. Awọn Ọmọ Israẹli ti jade kuro ni Egipti; wọn si dabi awọn ọmọ alakọbẹrẹ ninu ẹkọ. Bi apẹẹrẹ, bi eniyan ba n fẹ́ lati kọ́ awọn ọmọ alakobẹrẹ ni iṣiro, yoo mu ohun meji, yoo si pa wọn pọ̀; yoo wi pe ookan ati ookan jẹ́ meji. Bi wọn ba n fẹ lati kọ wọn ni pipin ẹyọ nnkan kan si ọna pupọ, wọn le mu eso kan ki wọn pin in si meji ni ọgbọọ-gba tabi si ọna ti o kere ju bẹẹ lọ, lati ṣe alaye bi apapọ awọn ẹya keekeekee wọnyii ṣe le di odindi. Ṣugbọn bi awọn ọmọde naa ba ti n ni òye si i, olukọni yoo bẹrẹ si i kọ alaye si ara patako nikan. Nigba miiran a kò tilẹ ni kọ ọ soke fun wọn; wọn ni lati ṣe iṣiro naa ni ori nitori wọn ti de ipo imọ̀ giga.

Bẹẹ gẹgẹ ni Oluwa ṣe bá awọn eniyan rẹ̀ lò. Awọn Ọmọ Israẹli n la igba alakọbẹrẹ já nipa ti ẹmi, Oluwa si n ba wọn lò gẹgẹ bi ailera wọn. O si fi awọn nnkan wọnyii lelẹ lati fi wọn ṣe alaye ohun ti ẹmi. Ṣugbọn wọn kuna lati wò rekọja alaye wọnyii. Wọn kuna lati ri Jesu Ẹni ti gbogbo rẹ̀ n tọka sí.

### Aṣọ Ikele

**"Jesu si tún kigbe li ohùn rara, o jọwọ ẹmi rẹ̀ lọwọ. "Si wo o, aṣọ ikele tẹmpili si ya si meji lati oke de isalẹ; ilẹ si mi titi, awọn apata si sán"' (Matteu 27:50, 51).**

Yiya ti aṣọ ikele ya yii n fi hàn pe ọna lati wọ Ibi Mimọ́ Julọ ṣi silẹ.

**"Ará, njẹ bi a ti ni igboiya lati wọ̀ inu ibi mimọ́ nipasẹ ẹjẹ Jesu,**

**"Nipa ọ̀na titun ati ãye, ti o yà si mimọ́ fun wa, ati lati kọja aṣọ kele ni, eyini ni, ara rẹ̀" (Heberu 10:19, 20).**

Aṣọ ikele ni jẹ́ apẹẹrẹ ara Oluwa Jesu Kristi, eyi ti a fàya nigba ti a kan An mọ́ igi. Ọna ṣi silẹ lati lọ sinu Ibi Mimọ́ Julọ, ifi Ẹmi-Mimọ́ wọni, eyi ti a kò i ti i fi hàn titi di akoko naa. Ifi Ẹmi-Mimọ́ wọni ni ohun naa ti o fi iyatọ hàn gbangba laaarin Akoko Oore-ọfẹ ati Igba Laelae ni ti awọn iriri nipa ti ẹmi eyi ti wọn kò ni ni Igba Laelae.

### Iriri Mẹta

Wọn ni idalare; wọn ni pẹpẹ idẹ eyi ti o wà ni iha ode Agọ, ninu àgbala. Eleyii jẹ́ apẹẹrẹ idalare nitori nihin ni wọn n mu ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ tabi irekọja wá; nigba ti ẹni ti o si mu ẹbọ yii wá ba mu u wa pẹlu igbagbọ́ ti a si fi rubọ gẹgẹ bi ofin, a ó dari awọn ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ji i. Bi o ba gba a pẹlu igbagbọ́, yoo ni iriri idalare tootọ gẹgẹ bi awa ti n ri i ni ibi pẹpẹ adura ni ọjọ oni.

A ri apẹẹrẹ Ibi Mimọ́ ninu Heberu 13:11, 12:

**"Nitoripe ara awọn ẹran wọnni, ẹ̀jẹ eyiti olori alufa mu wá si ibi mimọ́ nitori ẹ̀ṣẹ, a sun wọn lẹhin ibudo.**

**"Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin ibode",**

Olori alufaa mu ẹ̀jẹ akọ maluu lọwọ, a si lọ si Ibi Mimọ́, ki o to wọ Ibi Mimọ́ Julọ, yoo fi ẹjẹ naa sori iwo pẹpẹ wura. A sọ fun ni pẹlu pe Ofin fi lelẹ pe ki a mu awọn ẹran wọnni ti a mu ẹjẹ wọn wá si Ibi Mimọ́ ni lọ si ẹyin ibode ki a si sun wọn.

**"Nitorina Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ ara rẹ̀ sọ awọn enia di mimọ́, o jiya lẹhin bode."**

Ki ni ohun ti a le gba pe mimú ẹ̀jẹ lọ sinu Ibi Mimọ́ ati fifi ẹ̀jẹ naa sori pẹpẹ wura duro fun? Isọdimimọ́. A ni atilẹyin lati inu Iwe Mimọ́ fun eyi.

Ṣiṣi ti a ṣi iyara kẹta (Ibi Mimọ́ Julọ) silẹ ni akoko yii nipa kikàn ti a kan Jesu Kristi mọ́ agbelebu ki awa ba le fi igboya wọ ibi ti olori alufaa nikan maa n wọ̀ lẹẹkan lọdun, fun wa ni anfaani ti wọn kò ni ni igba Majẹmu Laelae. Ọna kan ṣoṣo ti a le tumọ eyi si ni iranwọ nlanla ti ifi Ẹmi-Mimọ wọni, nipasẹ eyi ti iná Ọlọrun yoo fi bà le wa gẹgẹ bi ẹla ahọn bi ti ina ti ba le awọn ọmọ ẹyin nigba ti Ẹmi Mimọ́ sọkalẹ ni Ọjọ Pẹntekọsti.

Ninu Agọ ni a fi apẹẹrẹ awọn iriri nla mẹtẹẹta ti Ọlọrun n fi fun ni hàn: Idalare, Isọdimimọ́, ati ifi Ẹmi-Mimọ́ wọni.

### Igba Atunṣe

**"Eyiti o wà ninu ohun jijẹ ati ohun mimu, ati onirũru iwẹ, ti iṣe ilana ti ara nikan ti a fi lelẹ titi fi di igba atunṣe" (Heberu 9:10).**

Ko ṣoro lati mọ akoko ti a pè ni igba atunṣe yii; eyi ni igba ti a o fi itumọ gbogbo nnkan wọnyii hàn kedere, Igba Oore-ọfẹ.

### Agọ Tootọ

**"Ṣugbọn nigbati Kristi de bi Olori Alufa awọn ohun rere ti mbọ̀, nipasẹ agọ́ ti o tobi ti o si pé ju ti iṣaju, eyiti a kò fi ọwọ́ pa, eyini ni, ti ki iṣe ti ẹ̀da yi" (Heberu 9:11).**

Ninu aginju ni a ti pa Agọ kin-in-ni; ṣugbọn Agọ tootọ ni eyi ti a sọ nipa rẹ̀ pé Oluwa ni ó kọ́ ọ ki i si i ṣe eniyan, ó wà ni Ọrun.

**"Nitori Kristi kò wọ̀ ibi mimọ́ ti a fi ọwọ́ ṣe lọ ti iṣe apẹrẹ ti otitọ; ṣugbọn o lọ si ọ̀run pãpã, nisisiyi lati farahan ni iwaju Ọlọrun fun wa" (Heberu 9:24).**

Gbogbo iṣẹ-isin Agọ ni a mu ṣẹ ninu Rẹ̀ nigba ti O bẹrẹ iṣẹ Alufaa Rẹ̀.

**"Bẽni ki iṣe nipasẹ ẹ̀jẹ ewurẹ ati ọmọ malu, ṣugbọn nipa ẹ̀jẹ on tikararẹ̀ o wọ ibi mimọ́ lẹ̃kanṣoṣo, lẹhin ti o ti ri idande ainipẹkun gbà fun wa" (Heberu 9:12)**

Olori alufaa a maa lọ sinu Agọ pẹlu ẹ̀jẹ nigbagbogbo. Awọn alufaa ko jẹ lọ si iwaju Ọlọrun lai si ẹ̀jẹ. Nitori naa o jẹ ohun pataki fun Jesu, gẹgẹ bi Olori Alufaa, lati mú ẹ̀jẹ lọwọ. Awọn alufaa a maa mú ẹ̀jẹ akọ maluu ati ewurẹ lọ. Nihin ni a ri imuṣẹ pipe fun iṣẹ-isin Agọ nigba ti Jesu wọ Agọ ti Ọrun, ti o si mú Ẹjẹ Oun tikara Rẹ̀ lọ lati fi bẹbẹ.

### Ẹ̀jẹ Jesu

**"Nitori bi ẹ̀jẹ akọ malu ati ewurẹ ti a fi nwọ́n awọn ti a ti sọ di alaimọ́ ba nsọ-ni-di-mimọ́ fun iwẹnumọ ara,**

**"Melomelo li ẹ̀jẹ Kristi, ẹni nipa Ẹmi aiyeraiye ti o fi ara rẹ̀ rubọ si Ọlọrun li aini àbawọn, yio wẹ̀ ẹri-ọkàn nyin mọ́ kuro ninu okú iṣẹ lati sin Ọlọrun alãye?" (Heberu 9:13, 14).**

Eyi fi hàn wa ohun ti ẹmi ti o wa ninu rẹ̀, pe nipasẹ Jesu Kristi ni a n sọ ẹri-ọkàn wa di mimọ. Nitori eyi ni ko ṣe si idalẹbi mọ́ fun awọn ti o wà ninu Kristi Jesu. Ẹri-ọkàn ni o n mu idalẹbi wá. Nigba ti a ba fọ̀ ọ mọ́ ti a si ti wẹ ẹ mọ́ kò tun si dalẹbi mọ́.

Ẹbọ ti Jesu Kristi ṣe iṣẹ de igba Ofin; o de ọdọ awọn Ju; bẹẹ ni o tún rekọja o si de ọdọ awọn Keferi. Etutu fun gbogbo ayé ni nipasẹ eyi ti a ti pese gbogbo iranwọ patapata lai ku ọ̀kan silẹ ti o si tó fun gbogbo aini. Gbogbo ayé ni o wà fun: awọn Ju ati awọn Keferi. Ki i ṣe bẹẹ nikan, o jẹ eyi ti a ti ṣe lẹẹkan ati titi lae. Ki i ṣe pe Jesu n wọle lẹẹkan ni ọdọọdun gẹgẹ bi olori alufaa ti maa n ṣe; ṣugbọn O ṣe e lẹẹkan ati titi lae, nipa bẹẹ o jẹ́ Etutu ayeraye, Etutu nla ti Jesu pese silẹ fun gbogbo ayé, wa fun gbogbo igba ati akoko.

Ninu gbogbo ibalo Ọlọrun pẹlu araye a ko le ri igba kan ti alailẹbi kú fun ẹni ti o jẹbi afi igba kan ṣoṣo yii ti Kristi Jesu kú fun awọn ẹlẹṣẹ -- olododo fun awọn alaiṣododo. A n ri aanu gbà niwaju Oluwa, ṣugbọn ki i ṣe nitori ohun rere kan ti o wà ni ayé wa. Iṣẹ-rere kiṣẹ-rere ti a ṣe, iṣẹ aanu-kiṣẹ-aanu ti a le ṣe, tabi inu rere kan kò le ra eyi ti o kere jù lọ ninu aanu Rẹ̀ fun wa.

Otitọ ni pe a o san ẹsan iṣẹ rere ti a ba ṣe fun wa. Kiki iṣẹ ti a ba ṣe ninu Ẹmi (ani kiki awọn ti a ṣe ninu Ẹmi) ni a o gba ere rẹ̀. Ṣugbọn a ko le ri aanu gba lọdọ Oluwa nipasẹ ohunkohun ti a le ṣe. Ọna kanṣoṣo ti ẹnikẹni le gbà ri oore-ọfẹ gbà lọdọ Oluwa (ati ọdọ ẹni rere ju lọ titi de ọdọ ẹni ti o buru ju lọ ninu awọn ti o n gbé ayé) ni nipasẹ Etutu ni.

### Majẹmu Titun

**"Ati nitori eyi li o ṣe jẹ alarina majẹmu titun."**

Ọrọ yii kan naa ni a tun tumọ̀ rẹ̀ ni ibomiran si “adehun” A le pe e ni Majẹmu Laelae ati Titun -- ọkan naa ni ọrọ̀ wọnyi. Ṣugbọn nihin yii o lo ọrọ ti a le pè ni “adehun” nitori o fẹ mu ohun miiran jade. Itumọ miiran ti a le fun iwe adehun ni ilẹ wa ni iwe ihágún ṣugbọn majẹmu yatọ si eyi. Nitori naa nihin yii o pe e ni adehun.

Lẹyin iku Jesu Kristi ni anfaani si iwe ihágún tabi iwe adehun Rẹ̀ ṣi silẹ a si gba a. Nigba ti O jẹ ounjẹ alẹ ikẹyin nì ti O si fi ago fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ O wi pe: “Nitori eyi li ẹ̀jẹ mi ti majẹmu titun” (tabi Adehun Titun ti a ṣẹṣẹ mú wá).

### Jijẹ́ Ọranyan Ẹjẹ Naa

**“Nitori nigbati Mose ti sọ gbogbo aṣẹ fun gbogbo awọn enia gẹgẹ bi ofin,. . . .”**

Ofin ni a kọkọ fi lelẹ, lẹyin eyi ni a kọ ọ sinu iwe kan ki a si mu u wá si iwaju awọn eniyan.

**“. . . . . o mu ẹ̀jẹ ọmọ malu ati ti ewurẹ, pẹlu omi, ati owu ododó, ati ewe hissopu,. . .”**

Hissopu jẹ́ igi kekere kan ti n hù ni ilu wọn lọhun, wọn a fi owu ododó we e wọn a si maa lo fun ibuwọn ẹ̀jẹ. Eyi ni Onipsalmu n sọ nigba ti o wi pé, “Fi ewe-hissopu fọ̀ mi, emi o si mọ́” (Orin Dafidi 51:7).

**“O si fẹrẹ jẹ́ ohun gbogbo li a fi ẹ̀jẹ wẹ̀nu gẹgẹ bi ofin; ati laisi itajẹsilẹ kò si idariji”.**

**“Nitorina a kò le ṣai fi iwọnyi wẹ̀ awọn apẹrẹ ohun ti mbẹ lọrun mọ́; ṣugbọn o yẹ ki a fi ẹbọ ti o san ju iwọnyi lọ wẹ̀ awọn ohun ọrun pãpã mọ́.” (Heberu 9:22, 23).**

Afi ẹjẹ akọ maluu ati ewurẹ sọ awọn apẹẹrẹ nnkan ti ọrun di mimọ́, ṣugbọn awọn ohun ọrun tikara wọn lati inu eyi ti a ti mu apẹẹrẹ ni o yẹ lati fi ohun ti o sàn ju eyi lọ sọ di mimọ́.

**“Nitori Kristi kò wọ̀ ibi mimọ́ ti a fi ọwọ́ ṣe lọ ti iṣe apẹẹre ti otitọ; ṣugbọn o lọ si ọ̀run pãpã, nisisiyi lati farahan ni iwaju Ọlọrun fun wa” (Heberu 9:24).**

### Awọn Ifarahàn ati Awọn Oyè Kristi

Ifarahàn mẹta ti o logo ni o wà ni opin ori iwe yii ti a fẹ yẹ wò. A o yẹ̀ wọn wò ni ṣisẹ̀-n-tẹle gẹgẹ bi wọn ti ṣe tẹle ara wọn dipo gẹgẹ bi a ti to wọn ninu ori iwe yii. Ekinni ni ẹsẹ 26:

**“Bi bẽkọ on ki bá ṣai mã jiya nigbakugba lati ipilẹ aiye: ṣugbọn nisisiyi li o fi ara hàn lẽkanṣoṣo li opin aiye lati mu ẹ̀ṣẹ kuro nipa ẹbọ ara rẹ̀.”**

Eyi n tọka si wiwá Rẹ̀ lẹẹkinni, eyi si ni idi rẹ̀ ti O fi wá: lati fi ara Rẹ̀ ṣe irubọ. Eyi ni idi pataki naa ti O wá fún. Lootọ ni pe O wá lati fun wa ni ẹ̀kọ́; O wá gẹgẹ bi aṣoju Ọlọrun ni ayé; O jẹ apẹẹrẹ rere; O kọ́ ni ni awọn ilana ti ọkàn gbogbo eniyan n jẹri si pe ilana rere ni wọn. Ṣugbọn eyi ki i ṣe ohyun pataki ju lọ ti O wá si ayé lati wa ṣe. Pataki ju lọ ati kókó ohun ti O wá ṣe ni pe O wá lati fi ara Rẹ̀ ṣe ẹbọ fun araye; nipa ọnà bayii nikan ni O le gba awọn ẹlẹṣẹ là. O gba ohun ti o to bayii ki O to le gbà wọ́n.

Ifarahàn keji ni a ri ninu ẹsẹ kẹrinlelogun:

**“Nitori Kristi kò wọ̀ ibi mimọ́ ti a fi ọwọ́ ṣe lọ ti iṣe apẹẹre ti otitọ; ṣugbọn o lọ si ọ̀run pãpã, nisisiyi lati farahan ni iwaju Ọlọrun fun wa”**

Eyi ni ifarahan Rẹ̀ keji. Eyi ni ayè naa ti O wà nisisiyii. Fun nnkan bi ẹgbàá ọdun (2,000) ni O ti wà lori Itẹ́ ni ibi ti O ti n ṣe alagbawi.

Ẹsẹ kejidinlọgbọn:

**“Bẽni Kristi pẹlu lẹhin ti a ti fi rubọ lẽkanṣoṣo lati ru ẹ̀ṣẹ ọ̀pọlọpọ; yio farahan nigbakeji laisi ẹ̀ṣẹ fun awọn ti nwo ọna rẹ̀ fun igbala.”**

Eleyi ni o kù ti a o mu ṣẹ nigba ti O bá pada lẹẹkeji. Wọnyii ni ifarahan nla Rẹ̀ mẹtẹẹta: wiwá ni ẹkinni lati fi ara Rẹ̀ ṣe irubọ; wiwọ Ibi Mimọ Julọ pẹlu Ẹ̀jẹ ara Rẹ̀; ati lẹyin eyi fifi Itẹ́ Rẹ̀ gẹgẹ bi Alagbawi silẹ lati gba ipò Rẹ̀ gẹgẹ bi Ọba. Ninu wiwá mẹta yii ni a ri awọn oyè Rẹ̀ gẹgẹ ti Wolii, Alufaa ati Ọba.